**OUNGBẸ TI ẸMI ATI OORE ỌLỌRUN**

**Orin Dafidi 42:1-11; 63:1-11; 65:1-13.**

**ẸkỌ 447 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Alabukún-fun li ẹniti iwọ yàn, ti iwọ si mu lati ma sunmọ ọdọ rẹ, ki o le ma gbe inu agbala rẹ wọnni: ore inu ile rẹ yio tẹ́ wa lọrùn, ani ti tẹmpili mimọ́ rẹ" (Orin Dafidi 65:4).**

I. **Oungbẹ ti Ẹmi ti Dafidi Ni ati Igbẹkẹle Rẹ̀ ninu Ọlọrun**
1. Ọkàn Onipsalmu kigbe si Ọlọrun, Orin Dafidi 42:1-4.
2. Nigba ti ọkàn rẹ̀ tẹba, ireti rẹ̀ wà ninu Ọlọrun, Orin Dafidi 42:5, 6.
3. Laaarin iṣàn wahala ati ipọnju, Ọlọrun yoo tù ú ninu, Orin Dafidi 42:7-9; Isaiah 43:2.
4. Nigba ti awọn ọta rẹ̀ bá n kẹgan rẹ̀, Ọlọrun yoo ṣe iranlọwọ, Orin Dafidi 42:10, 11; Matteu 5:10-12.

II. **Ifẹ ọkàn Dafidi fun Isin Ọlọrun ninu Ibi Mimọ́**
1. Oun yoo wá Ọlọrun, agbara Rẹ̀ ati ogo Rẹ̀, Orin Dafidi 63:1, 2; 27:8.
2. Oun yoo yọ̀, yoo si yin Ọlọrun fun iranlọwọ Rẹ̀ ati awọn ibukun Rẹ̀, Orin Dafidi 63:3-8; 91:4.
3. Awọn eniyan buburu ni a o pa ni ẹnu mọ́, Orin Dafidi 63:9-11; 101:7.

III. **Oore Ọlọrun**
1. A gbadura si Ọlọrun a si fi iyin fun Un; Oun wẹ ẹ̀ṣẹ nù, Orin Dafidi 65:1,2
2. Alabukún fun ni ẹni ti Oluwa yàn, ti o si sún mọ ọdọ Ọlọrun, Orin Dafidi 65:3; Johannu 15:16.
3. Agbara ati ipá Rẹ̀ mu ki awọn eniyan ki o bẹru Rẹ̀, Orin Dafidi 65:4-8.
4. Ọlọrun fi oore ati ibukun Rẹ̀ bẹ gbogbo ilẹ ayé wò, Orin Dafidi 65:9-13; Iṣe Awọn Apọsteli 14:17.

## ALAYE

### Ilepa ti Ẹmi

Onipsalmu, nipa ṣiṣe afẹri Ọlọrun, n ṣe ohun ti a dá eniyan sinu ayé lati ṣe. Ọlọrun dá eniyan fun igbadun ara Rẹ̀. A dá a ki o ba le wà ni irẹpọ pẹlu Ọlọrun Rẹ̀; imuṣẹ ilepa rẹ̀ ninu ayé si ni lati wà ninu fifi ayọ̀ wà niwaju Ọlọrun, ati ninu ipese iyanu Ọlọrun fun gbogbo ifẹ ọkàn rẹ̀ fun ohun rere gbogbo, ati lati tán gbogbo aini rẹ̀. Ayọ̀ ati irẹpọ ti Adamu ati Efa ni pẹlu Ọlọrun ninu Ọgba Edẹni ko ṣe e diwọn rara. Ati lati igba ti wọn ti sọ irẹpọ ni nù nipa iṣubu wọn, ni gbogbo eniyan ti n ni ohun kan ninu ọkàn wọn ti o n mu ki wọn mọ̀ pe Ọlọrun ni ọkàn wọn n fẹ́, yala wọn gbà pe otitọ ni eyi tabi bẹẹ kọ́. Gbogbo awọn ti o ba tẹle oungbẹ ọkàn wọn yii ni o n irẹpọ didun pẹlu Ẹlẹda wọn, iru irẹpọ ti Ọlọrun n fẹ ki gbogbo eniyan ni gbogbo ayé ni. Bi eniyan ba ti mọ Ọlọrun to, bẹẹ ni oungbẹ n pọ̀ to ninu ọkàn rẹ̀ lati fẹ mọ̀ Ọ́n ju bẹẹ lọ. Bi akoko ti a ba lo pẹlu Ọlọrun ninu adura ba ti pọ to ni ifẹ ati tubọ gbadura siwaju si i n pọ to, a si maa fun ni ni ayọ ti o pọ̀ rekọja nigba ti a ba wà niwaju Rẹ̀. Isopọ ati irẹpọ pẹlu Rẹ̀ nihin jẹ́ itọwo ayọ̀ ti a o jẹ igbadun rẹ̀ nigba ti a ba dé iwaju Rẹ̀ ti a o si maa bá A gbé ni Ọrun titi ayé.

A ṣe akiyesi pe lati igba ayé yii ti wà, gbogbo awọn wọnni ti ebi ẹmi ba n pa ni o maa n ri ohun rere Ọlọrun ti o dara ju lọ gba. Gbogbo awọn ti o ba fi ainaani tabi ọwọ dẹngbẹrẹ mu ohun ti ẹmi ki i pẹ kú ikú ẹmi a fi bi wọn ba bẹrẹ lati maa fi ohun ti i ṣe ti Ọlọrun ṣe akọkọ ni igbesi ayé wọn, ki wọn si maa fi tinutinu wọn wá ohun ti Ọlọrun. Gbogbo wa ni o ni ohun kan ti ọkàn wa n fẹ́, ṣugbọn

o ṣe pataki fun wa lọpọlọpọ lati maa ṣafẹri ohun ti ẹmi, eyi ti ki yoo le fi àye silẹ fun ohun ti ayé ti o n de ọpọlọpọ eniyan ni igbekun ti ó si n sọ wọ́n di talaka nipa ti ẹmi.

Onipsalmu ni ayọ̀ ninu ọkàn rẹ̀ nipa ti anfaani ti o ni lati maa lọ si ile Ọlọrun. O n yọ̀ nibẹ, ireti si wà ninu ọkàn rẹ̀ ani nigba idanwo. O wi bayii ninu Orin Dafidi 122:1 pe “Inu mi dùn nigbati nwọn wi fun mi pe, Ẹ jẹ ki a lọ si ile OLUWA”. A pa a laṣẹ fun wa ninu Ọrọ Ọlọrun lati maa wá si ipade, “Ki a má mã kọ ipejọpọ̀ ara wa silẹ, gẹgẹ bi àṣa awọn ẹlomiran; ṣugbọn ki a mã gbà ara ẹni niyanju: pẹlupẹlu bi ẹnyin ti ri pe ọjọ ni nsunmọ etile” (Heberu 10:25).

Oungbẹ ti ẹmi ti Ọlọrun n fẹ ki o wà ninu ayé wa yoo maa mu wa yọ̀ ninu anfaani ti a ni nipa eyi ti a le maa bá awọn eniyan Ọlọrun pejọ pọ̀ ti a o si maa wà ni irẹpọ pẹlu wọn. Ẹnikẹni ti o ba ni ifẹ yii ninu ọkàn, yoo maa fi tifẹtifẹ wá si ipade lai jẹ pe ẹnikẹni rọ ọ lati wá, ifẹ ọkàn rẹ̀ yoo jẹ lati gbọ́ Ọrọ Ọlọrun, lati gbọ́ iyin Ọlọrun ti o n jade lati ẹnu awọn ẹni irapada Ọlọrun, ati lati ni anfaani lati bá awọn ti o tun ni iru ifẹ bẹẹ ninu ọkàn wọn gbadura.

### Igbẹkẹle ninu Ọlọrun

Ani nigba ipọnju, nigba iji lile, a mu un dá Onipsalmu loju pe Ọlọrun ki yoo kọ ọ silẹ. Ọlọrun yoo wà pẹlu rẹ̀ nigba ọsán, ati nigba oru Ọlọrun yoo fun un ni orin. Ninu Orin Dafidi 91:7-11 o wi bayii pe: “Ẹgbẹrun yio ṣubu li ẹgbẹ rẹ, ati ẹgbarun li apa ọtún rẹ: ṣugbọn ki yio sunmọ ọdọ rẹ. Kiki oju rẹ ni iwọ o ma fi ri, ti o si ma fi wo ère awọn enia buburu. Nitori iwọ, OLUWA, ni iṣe ãbo mi, iwọ ti fi Ọga-ogo ṣe ibugbe rẹ. Buburu kan ki yio ṣubu lu ọ, bẽli arunkarun ki yio sunmọ ile rẹ. Nitori ti yio fi aṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ, lati pa ọ mọ́ li ọ̀na rẹ gbogbo”. Iru awọn ileri bayii kọja agbara ẹda, wọ́n si fi hàn fun ni bi aanu Ọlọrun wa ti pọ to ati bi O ti ni ifẹ to lati ṣe wa loore.

Ninu awọn ti o gbẹkẹle Ọlọrun, Jobu jẹ́ ọ̀kan ninu awọn apẹẹrẹ ti o dara jù lọ ti a le ri ninu Bibeli. Nigba ti o ti sọ ohun gbogbo nù, o wi bayii pe: “OLUWA fifunni, OLUWA si gbà lọ, ibukun li orukọ OLUWA” (Jobu 1:21).

Lẹyin eyi a fi oowo pọ́n ọn loju lati atari ori rẹ̀ titi de ẹsẹ̀ rẹ̀, ṣugbọn ninu gbogbo ipọnju rẹ̀, “on kò ṣẹ̀, bẽni kò si fi were pè Ọlọrun lẹjọ”. Ọlọrun san ẹsan igbẹkẹle rẹ̀ fun un, o si mu un jade pẹlu ibukun ti o pọju eyi ti o ti ni ri ṣaaju, igbẹkẹle ti o ni ninu Ọlọrun kò si yipada.

Onipsalmu mọ iru igbẹkẹle ati iṣẹgun bayii bi o tilẹ jẹ pe ipọnju ti rẹ̀ yatọ si ti Jobu. Bakan naa lonii ni olukuluku Onigbagbọ́ n ri ayọ̀ ati iṣẹgun ni gbigbẹkẹle awọn ileri Ọlọrun. Awọn ohun wọnni ti Jesu ṣe nigba ti O n rin leti okun Galili, yoo ṣe e lonii pẹlu. “Jesu Kristi ọkanna ni li aná, ati li oni, ati titi lai” (Heberu 13:8).

### Oore Ọlọrun

O ṣoro fun eniyan ẹlẹran ara lati le mọ jijin ibú oore ati titobi Ọlọrun. Ko si ohun ti oun le ṣe ju pe ki o maa yin In ninu adura, ninu orin ati ninu isin. Pupọ ninu awọn orin ayebaye ti a fẹran ju ni o ti sọ nipa oore Ọlọrun ati aanu Rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan, pupọ ninu awọn orin wọnyii si jẹ́ alaye awọn iyin ti Onipsalmu kọ.

Ninu awọn psalmu a kà nipa Olugbala ati idariji Rẹ̀ fun awọn ẹ̀ṣẹ wa. Njẹ a tun le ni ifarahan ifẹ Ọlọrun si wa ti o pọ ju eyi lọ! Ni tootọ gbogbo Bibeli, eyi ti awọn Psalmu jẹ́ apa kan rẹ̀, n sọ nipa Ọlọrun, ifẹ ati itara Rẹ̀ fun awọn ọmọ eniyan, ati ifẹ ọkàn Rẹ̀ lati ṣe wọ́n ni ire. Bi ẹnikẹni ba gbẹkẹle agbara ara rẹ̀, ko si ẹni ti o le gba ara rẹ̀ là, ṣugbọn nitori ifẹ Ọlọrun ni rirán Jesu wá lati kú nitori ẹda, ẹnikẹni le ni alaafia pẹlu Ọlọrun ati ilaja nipasẹ Jesu Ọmọ Rẹ̀.

Bi o tilẹ jẹ pe ẹṣẹ si Ọlọrun Mimọ yii to lati rán ọkàn lọ si ọrun apaadi o si buru lati rò nipa rẹ̀, sibẹ ohun iyanu ni lati mọ̀ pe ọkàn kọọkan ti o ba wà ninu wahala le ri isinmi nipa ironupiwada si Ọlọrun ati igbagbọ́ ninu Jesu Kristi Oluwa. Ẹlẹṣẹ mọ ẹbi rẹ̀ nigba ti o ba wo Jesu ati nipasẹ Jesu ni o n ri idariji ti o si n ni ọkàn ti o mọ́ gaara bi ẹni pe ko dá ẹ̀ṣẹ ri. Oun yoo bẹrẹ si i mọ oore Ọlọrun

igba gbogbo lori rẹ̀, agbara Ọlọrun yoo si pa a mọ́. " Iwọ o pa a mọ li alafia pipé, ọkàn ẹniti o simi le ọ: nitoriti o gbẹkẹle ọ" (Isaiah 26:3).

A le fi ipamọ ọkàn wa lé Oluwa lọwọ lai bẹru. Awọn ti o ba tilẹ dide si wa, Ọlọrun yoo dá wọn lẹjọ. Ko ṣanfaani lati da ara wa laamu tabi mu abawọn bá ọkàn wa nipa nini ẹmi igbẹsan. Ọlọrun rán Ọmọ Rẹ̀ lati kú fun wọn pẹlu. Ti wa ni lati fẹran wọn ati lati wò wọn bi ẹni ti Oluwa kú fun. Ọlọrun yoo dá wọn lẹjọ ki i ṣe nitori wọn bá awọn eniyan Ọlọrun jà nikan ṣugbọn nitori wọn fi igba gbogbo kọ aanu Ọlọrun ti O ran si wọn.

"Olufẹ, ẹ máṣe gbẹsan ara nyin, ṣugbọn ẹ fi àye silẹ fun ibinu; nitori a ti kọ ọ pe, Oluwa wipe, Temi li ẹsan, emi ó gbẹsan" (Romu 12:19). Ninu awọn ibukun ti o wà ninu apa kin-in-ni ori karun-un Matteu, a ka bayii pe: "Alabukún-fun li awọn ẹniti a ṣe inunibini si nitori ododo: nitori tiwọn ni ijọba ọrun. Alabukún-fun li ẹnyin, nigbati nwọn ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibinu si nyin, ti nwọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi. Ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o si fò fun ayọ̀: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun: bẹ̃ni nwọn sá ṣe inunibini si awọn wolĩ ti o ti mbẹ ṣaju nyin (Matteu 5:10-12).

Ọlọrun n rán ibukun Rẹ̀ ani sori awọn ti o tilẹ jẹ́ alailọpẹ. Gbogbo ẹda alaaye ni o ni eredi ti wọn fi ni lati maa yin Ọlọrun fun awọn ibukun Rẹ̀. I ba ti dara pupọ bi wọn ba le mọ̀ pe ọwọ́ Ọlọrun ni ibukun wọn ti n wá! Wiwà laaye wa, ibukun Ọlọrun ni. Fọnran owu ayé wa wà lọwọ Rẹ̀. Nitori naa ayọ̀ ti a n ni pẹlu awọn ọrẹ wa ati awọn ẹni ti a fẹran ṣe e ṣe nitori Ọlọrun ni o fun wa ni ẹmi wa lati lò ati lati jẹ igbadun rẹ̀. Ilera wa, ibukun ni. O dara pupọ ju lati jẹ igbadun oore Ọlọrun nipa ilera ju ati ni iwosàn kuro ninu aisàn buburu ti Eṣu rán si wa. Bi o tilẹ jẹ pe oun, ani eṣu n fẹ mu ibi pupọ bá wa ṣugbọn Ọlọrun ni O n ṣe akoso rẹ̀ ti o si n dín agbára rẹ̀ kù. Eṣu kò le kọja ibi ti Ọlọrun fun un ni aṣẹ dé. Ibukun ni eyi paapaa ani fun ẹlẹṣẹ pẹlu, ṣugbọn nitori wọn kò ri i, ko jẹ ki wọn mọ riri rẹ̀. Ṣugbọn ọmọ Ọlọrun ti o mọ gbogbo nnkan wọnyii ti o si n dupẹ lọwọ Ọlọrun nitori wọn, ninu idupẹ yi, o n ni ibukun kún ibukun. O jẹ́ didun ọkàn rẹ̀ lati maa yin ati lati maa fi ogo fun orukọ Oluwa.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ileri fun ọkàn ti ebi n pa?
2. Bawo ni eniyan ṣe sọ ibarẹ didùn pẹlu Ọlọrun nù ni iṣaaju?
3. Ki ni ṣe ti olukuluku eniyan ṣe n ni oungbẹ lati mọ Ọlọrun?
4. Bawo ni eniyan ṣe le sọ ifẹ rẹ̀ fun ohun ti ẹmi di pupọ ati kikún?
5. Ki ni ṣe ti Onipsalmu ṣe n ni inu-didùn ni lilọ si ile Ọlọrun?
6. Darukọ diẹ ninu awọn ohun wọnni ti gbogbo wa ni lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fún?
7. Njẹ nitori ti awa ni ẹtọ si awọn ohun rere ni a ṣe n ri wọn gbà?
8. Ki ni ṣe ti a n ri wọn gbà?